ENMO KILEYI O, ERAN D'ENIA!

**Ikede**

Aso Ikede yi f u n gbogbo ẹnyin Onkawe wa ati asoju wa wipe, ẹni kẹni ti owo ba sẹku si owo rẹ ki o tete fi ranṣẹ nitori gbogbo ohun elo ti a fi nṣẹwe Irohin lo ti gbe owo leri.

Enikeni ti ko ba fi tirẹ ranṣẹ ao da Iwe rẹ duro no si ni agbara lati gba owo wa ni owo re. Olotu

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

**Asayan Oro**

Oro ti o mba mo-ko-moro wa
Enia t'o nso Igba d'Ogbun, Ogbun ki iso l'oko enikan

VOL. VII No. 423 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA JULY 9 1955, IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI. (2d

## Egbe Alakuko Jomi Lowosi.



**Ilesha** Irohin ti a gbo lati Ilesha ni wipe Oba Adeniran Adeyemi, Alafin Oyo so fun asoju Iwe Irohin to ranse pe wipe, ohun ti on nfe ni ki awon Egbe Alakuko (NCNC) lo sinmi agbaja nidi oro on pelu Ijoba - Iwo - Orun, ki awon Egbe Alakuko mase fi oruko on se itaja fun egbe won mo. Eyiti nwon ba on se ninu regbodiyan na to ge e, ki olukuluku lo so agbeje mo'di arare.

Oba Alafin tun so wipe on ko ni fi ese kan tayo ohun ti Ijoba Iwo - Orun ba se, on yio si ma gboran si awon oba ile Yoruba yoku lenu, on ko ni koja won.

Oba Alafin wipe on ki ise omo egbe N.C.N.C. ati egbe *Afenifere* (Action Group) Baba Egbe Omo Oduduwa ni on ise, nipa ti edeaiyede to mbe larin on pelu awon enia on, enikeni ti o ba ni ife ki on pada si Oyo, ki oluware lo sowopo pelu awon enia on - Egbe Omo Oduduwa.

On ko ni koja ohun ti Ijoba Iwo - Orun ba se.

Eyi fi han gedegbe wipe Oba Alafin ti ri iyato to wa ninu ohun dudu ati funfun, o si se ikede to yanju fun olukuluku awon enia to nse atilehin fun u ni ona to lodi si eto wipe ki nwon lo so agbeje mo'di nidi oro on pelu awon enia re.

KUTA - KUTA PIN.




## Enmo Kileyi o, Eran-d'enia !

Irohin aramada kan ti a gbo ni wipe ni ilu kan l'ona ile Wukuwuku, okunrin kan mbe ni Ileto kekere kan to je opidan enia, o ni ogun gidi lowo. Bi enia ba ri oju wompari okunrin na, bi ko ba je eniti okan re le, yio bu rele.

Ni ojo kan, nigbati okunrin yi bere si pidan, o di Kiniun, nigbati a ti le yipada di enia di ohun aseti fun u, l'o ba be sinu igbo.

Lehin opolopo odun, ni okunrin na yo si Abule re atijo. O se wahala ti-ti, o wa di idaji eranko, idaji enia, lati ibara-idi to fi de ori je enia, iyoku lo si isale je eranko. Awon enia to wa li Abule ri i, nwon fi ese fe e, oro di b'olo, yago fun mi.

Ki Olorun maje ki agba tan lori ile aiye, ajulowo adura ni; nigbati gbogbo enia salo kuro l'Abule fun abami enia yi, ni baba kan to je agbalagba ninu Abule na, wipe ki on to sa, on yio foju kan ohun ti yio le on.

Baba yi loduro ti okunrin yi fi sunmo, to si so idi abajo fun u, nigbana ni baba to nlo wa awon enia kiri lokokan, wipe ko si ewu o, e wa wo o, boju ri oro awofin.

## Sara Lebo Imale

L'ojo Satide, ojo keji osu July yi, Alakoso Ise Iwe Irohin wa, (Our Managing Director) kowa l'enujo, nipa jije mimu to fi se sara fun ilosiwaju Ise Iwe Irohin wa yi.

Nibe lojo na, A'ufa Abudu Rahman lo se adura si Oluwa fun ibukun Re lori ise wa, o si toro emi gigun ati alafia ara fun alakoso wa Ogbeni Tajudeen Thompson ati gbogbo awa osise pelu aaya to dara ninu Alukurani mimo, lehinna ni gbogbo wa se fatiya. Ki ibukun Olorun ati alafia ki o ma ba gbogbo wa gbe. Amin.

Nigbati awon enia wa bere faaji, jowo enikeji, "oku adie ko mo eniti o tu on" gbogbo nkan wa ndun yungba bi eni to nfi oyin muko. Igbadun ojo Satide na kagara, lai ko pe ilu, ase awon omo wa mo enu fi se ilu jo ju ilu paapa lo.

A ko le se alaidaruko die ninu awon to peju - pese sibi ariya sara na, awon enibi :- Ogbeni S. Ademiju, L. A. Ojo, W. A. S. Odebiyi, W. Adesina, Wahab Ola, Sulu, R. A. Subair, S. A. Majeorahun (alais Ofe) E. O. Folaranmi, Tunde Williams (alais Small Boy) S. Ola, Koleosho, Bashiru Olukotun, Y. B. Oki, ati awon sanmori enia ti a ko le daruko tan.

Awon Yoruba l'o ma npalowe wipe " Ebo kekeke l'o ma ngba alaiku la." Sara l'ebo Imale.

KI OLODUMARE GBA ADURA WA.

# ELETI QFE

A-NIJU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28 Kosoko Street Lagos
P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS
"ETI-QFE LAGOS"
Phone 23370

VOL. VII NO. 423 LAGOS SATURDAY JULY 9 1955.


## Ibukun Ni Fun Eniti Nse It'ore Anu

A fe fi wosika wa ose yi se alaye die niba ranpe fun enyin okawe wa, nipa itore anu, gegebi o ti ni ibukun oluwa pupo, benani o si ni iyi lodo awa eda enia.

Bi itore anu ti je ohun pataki to, ni Qlorun Qba Alaye paapaa fi kan nipa fun awa eda owo Re ninu Alkoran Mimo, wipe ki a ma se itore anu, fun awon atoroje ti a npe ni Onibara, o si se ileri wipe bi a ba fi kobo kan se itore anu On yio fi ilopo mewa ro'po kobo kan na fun wa.

Bakanna l'o si tun wa ninu Iwe Mimo Bibeli ti awon elesin Igbagbo ti Qlorun tun so wipe Ibukun ni fun awon eniti o nfun alaini, ao si ma bukun ise owo won. Awon Yoruba ni ma so wipe 'Ebo ke-ke-ke l'ongba alaiku la" ati pe sara l'ebo ti awon Imale, awon ti a wi wonyi ko je boju wo ehin ti nwon ba fe se itore anu ti won.

Ohunkohun ti enia le ni lode aiye, ti o ba le roju ma se itore-anu ninu ohun ini re na, owo Oluware yio ma roke ni, ko ni se ti, tabi-tabi ko si ninu iyen- o daju.

Irufe iwa rere bayi ni alakoso ise Iwe Irohin wa Eleti-Qfe se ni ojo Satide to koja, ti a se irohin re niba soki si apakan Iwe Irohin wa ose yi, a be Qlorun, a fi Anobi Re be, ki o ma sai ro'jo Ibukun Re sile Alakoso wa, sori Ise Iwe wa, ati sile olukuluku wa kari o.

Asalatu Nobiyi Karim.

## Okunrin Kan Gbeyawo Li Qgba Ewon

Qkunrin kan ara Kukuruku ti Ijoba gbe ju si ewon nitoripe o jale, nwon fi si ewon odun marun. Obirin kan ewe si ti mbe ni ogba ewon ki ara Kukuruku to de, fun esun wipe o sesi pa enia, nwon fi si ewon odun mewa

Samo-samo, awon mejeji yi ti loro pelu ara won. Nigbati ojo pe ti okunrin ara Kukuruku na fe jade kuro ninu ewon, o so fun Qga ile ewon wipe, on fe gbe iyawo on li arede ki on to jade.

Qga ile ewon ranse pe Alufa Sesi, nwon si soyigi fun awon mejeji, ehin ti Alufa pari gbogbo eto tan ninu ogba ewon, nwon jeki obinrin na lo wakati meji pelu oko re, ninu yara kanna logba ewon.

Lehin eyi, nwon da okunrin na sile wipe ki o ma lo kuro li ogba ewon nitori akoko ti o ni lati lo logba ewon ti to. Sugbon ti obirin si ku Qdun meta abo.

Ko ju iwon odun kan lo lehin eyi, Ijoba ranse si okunrin ara Kukuruku na wipe awon ba yo gidi-gidi nitori ti iyawo re bimo.

O pada lo si ogba ewon lati lo ko omo re jade ijoba si gba fun lati se be. O ra emu lopolopo awon elewon si ba ko omo na jade, sugbon Alufa to se igbeyawo fun won, na lo ko omo na jade, nwon si fun omo na ni oruko ye Ewong-bemi. Ijoba fori odun meji abo to ku jin obinrin na, nwon si ni ki o ma ba oko re lo sile.

Qlorun ko da Ewon-gbemi si.

## Ojubo Oduduwa Kan Mbe Ni Ijebu Ife

Lati Qwo ESO IKOYI

Afefe li o nse origi yeriyeri, Efufu li o nse ori agbon ni koro, ni koro, a difa fun Odudua a bu fun Orunmila lojo ti a ranse pe won li orun wipe ki nwon yara ma bo wa, Orunmila ru ki o to bo soju o n a, sugbon oduduwa ko ru. Nigbati awon mejeji de orun, nwon ni ki Oduduwa joko ki Qrunmila na ma lo tun ile aiye se. Egbera.

Ko nse itan bi odu Ifa yi tise sele ni mo fe lo loni', Awon Opitan so fun wa wipe, awon Irumole a ma takun lo si orun, nwon o si ma takun wa sile aiye. Ohun ti a fe so loni ni wipe, kini okun na tiri, nibo ni okun na wa, bawo ni Ade ti Oduduwa de gbehin ti ri?.

Bi a ba ranse pe I g b a mole, gbogbo won li ojijo nro lo si orun, bakanna ni nwon jijo npada bo. Sugbon Ohun ti o jeki ewon ti nwon fi nro lo si orun wa nile aiye ni wipe, nigbati Orunmila ati Oduduwa de orun, nwon ni ki Orunmila nikan ma bo wa sile. Enikeni ti o ba nfe ri Ojubo Oduduwa ki o lo si odo Alaiyeluwa Ajalorun, oba Ijebu Ife.

Nibe ni iwo yio ti fi oju ri ewon na, eyiti awon Irumole fi nro lo si orun, Opon ti nwon fi ngba eje si, Odo mojalake ti a npe ni Qtererc ati Otarara.

Qgbeni Alagba k a n ti a npe ni D. O, Adeniga li o nse aayan pupo pelu awon egbe ti o nfe Ilosiwaju Ijebu Ife,, lo se alaye nipa ojubo Oduduwa yi, o si se aworan awon ohun ti ko ye lati ma fi oju ri nigba gbogbo

Ninu aworan yi iwonyi ni awon ohun ti o mbe ni ajubo Oduduwa fi o je ohun asiri, Agogo, Ilu aran, i l u gbedu Ewon. Awon obinrin Aguren, ati awon ti o nlo si odo Mojaleke, Orisirisi aso ti a ta soju Oduduwa, ati opolopo awon nkan miran bi Oletu Osere, Oletufore ede ti nwon fi nki ara won nibe. ibiti enia ko gbodo pade ara won.

Iye owo ti Qgbeni Adeniga ti nna lori nkan yi nlo bi iwon Qgorin Ponun, o si ku iwon odunran Ponun lori re lati na.

## Awon Ilu Ile Yoruba

Awon Yoruba ni orisirisi ilu ti nwon ma nlu fun ariya gbogbo awon ilu bi Dundun Aporan Gangan, Sekere, Aro Bata, ati ilu Agbe.

Gbogbo awon ilu wonyi l'o ni awon eroja won ki o to kan eyiti a npe ni Iya-Ilu orisirisi ni awon to nlu awon eroja wonyi, awon ni a npe ni Olomele ilu, awon miran nto meta, merin tabi ju be lo

Ilu Bata je ilu ti awon Elegungun atiOnisongo feran ju, lako-lako si ni nwon njo ijo re. Ere ilu Agbe lo dun jojo, nitoripe o ma nni idan pipa ninu tabi ki won ma gbe okiti.

Yoruba feran ariya pupo, nibi isinku, igbeyawo, ise esin Qlorun, ko si ohun ti Yoruba ki I fi ilu se.

## Enmo Kil'eyi o!

Ni ojo ose tokoja l'agbe wipe won ri oku okunrin kan, omo - odun merinlelogoji to na gbalaja si egbe irin oko - ile (Railway) ni Mushin, awon onisec - oba ti gbe lo fun ayewo.

Lojo kanna ni owon tun ji ba oku oyinbo kan ti oruko re nje Albert Amor, alabojuto ile kiko l'abe awon oyinbo akole ti a npe ni Kapa ati Dalibato lori ibusun re (Bed) ninu ile ti o ngbe ni Ikorodu Road' l'oke Ebute Metta. Nwon ti gbe oku na lo fun ayewo.

Kil'o ha le fa iru iwonyi wa o, Oluwa!



OLOYE S. L. AKINTOLA



OLOYE QBAFEMI AWOLOWO

**Nigbati nwon se atunse Ibudo - Ile oko-ile ti Ilu Ibadan tan, (Railway Station) awon Olola Oloye, Obafemi Awolowo ti ise olori Egbe Afenifere ati Oloye S. L. Akintola ti a nwo aworan won l'oke iwe yi lo fi ola won bukun isile Oko - Ile na.**

WESTERN REGIONAL PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

**AGRONOMIST**

The Western Regional Production Development Board, Ibadan, Nigeria, invites applications for the position of Agronomist. The duties of the successful applicant will be to maintain liaison with all West African Research and soil survey organisations and to co-ordinate all cultural, fortilizer, and sundry experimental work required in connection with the Board's commercial plantations of Cocoa, Rubber, Oil Palms, Citrus and other tropical crops. Candidates must possess a good degree in Science or Agriculture, preferably honours, with some knowledge of Chemistry or Soil Science, and should have several years post graduate agronomic experience preferably in the tropics.

Salary will be in the range of £1,240 to £2,100 per annum (including; expatriation allowance where appropiriate), point of entry depending upon candidates qualifications and experience; outfit allowances £60, free medical services; free passages for wife and up to two children or children's separation allowance at the rate of £75 per annum per child; free house with basic furniture; up to 10 o/o Provident Fund; home leave on full pay at the rate of five days per month of overseas service; tour initially 18/24 months with good prospects of renewal.

Applications, preferably in the candidates' own handwriting stating age, family, qualifications, practical experience in chronological order, present salary and address to the secretary, Western Regional Production Development Board, Ibadan, Nigeria, not later than 15th July 1955.

Eleti Qfe Lo Ri Ghogbo Ile Nile Nigeria Ati Ni'lu Okere,

W... P... wo Oja Re Sinu Eleti Qfe

## E Ronu Piwada, Nitori Ijoba Orun Ku Si Dede.

OLOTU,

Jowo gbami laye lati se alaye die nipa oro oke yi ti Lemomu Ajakuta so, a ti se alaye oro yi ninu Adisi Anobi Yisa, ike ati ige Qlorun ko ma ba.

Ninu tira na, awon omo ehin Yisa (Jesu) bere lowo re wipe, o ti le li odun marun ti o ti nso wipe ijoba ku si dede, li ojo wo gan ni ijoba na yio de, ki nwon le mura sile dee.

Anobi Yisa dahun pe, eniti ojo iku tire ba pe ni ijoba orun tire de.

Sugbon opolopo enia nsi oro na gbo, nwon rope, ojo ti Olorun yio se idajo orun ati aye ni anobi Yisa nwi.

E ronu piwada nitori ijoba Olorun ku si dede eniti o ba ronu wo wipe, iwa aidara ni on nhu, ti o si pinnu lati ko iwa buruku na sile ki ojo iku to de, oluwa re li o jere nitori idariji ko si ninu isa oku.

Emi ni
Malam Garuba Goroso
Kasina College

## Idahun Si Ibere Oyewole Niyi

Qlotu,

Gegebi ohun ti Ogbeni Oyewole bere nipa awon oro ti Jesu ko so, ti awon enia nso wipe Jesu lo so o.

1. Jesu ko so wipe omo Qlorun ni on, sugbon awon Onigbagbo li o npe e li omo Qlorun. Bi Jesu ba pe Olorun ni Baba, ko nse wipe Olorun li o bi. Bakanna si ni eda enia npe Olorun ni baba, o ha nse Olorun li o bi nwon dan?

2. Jesu ko pe ara re ni Olugbala nitoripe o mo wipe Olorun nikansoso ni Olugbala ohun ti Jesu wi ni wipe, ki awon Ju gba on gbo gegebi ojise Qlorun, nitori ko s ona miran ti enia le fi la.

3. Awon Onigbagbo tun so wipe Jesu wa li owo otun Qlorun, Tani eniti o lo si orun ti o si tun pada wa rohin wipe on ri Qlorun joko Jesu si joko lapa otun re. Bi Johanu ba riran, iran yato si Ododo oro,, nitori oju ti o ba ri Qlorun, ko ni je enia mo. Mose ti Qlorun mba soro loju koroju ko ri Qlorun ambosi-bosi Johanu.

Lemomu Ajakuta.

## Owo Abetele.

Lati owo Lemomu Ajakuta.

Abetele ki nse ohun ti o sele nile Yoruba, nitori wipe awon Onise Ijoba ti o mbe larin wa nigbani ko fi iwa Abetele ko wa. A ko mo iru iwa be, a ko si nse e.

Lati ipilese wa, ise Agbe ni Yoruba nse, sugbon nigbati awon Oyinbo Reluwe ti bere ise won, ti nwon gba opo enia si ise Lebira, gbogbo enia ko ise agbe sile.

Bi enia ba jeun yo, ko si ohun kan ti yio tun wu oluwa re je. Ati pelu, bi enia ba ngba owo ti o kaju bukata ti o seku, oro ati gba owo abetele ko ni wa si okan re.

Awon Qlopa, Panopano, Soja ti nwon nsise ribi-ribi fun alafia ilu ye ki nwon ma gba owo geregere. Bi owo awon enia nwonyi ba ga, enia pupo ti o je omowe yio ma yara lati wo ise na. Bi owo ba po ninu ise kan, bi o ti wu ki wahala ise na po to, nwon o ma fi ori ti i.

Sugbon nigbati enia ni iyawo, omo, ati awon obi, ti o si ngba owo ti ko kaju bukata, nigbawo ni oluwa re yio ri aye ran omo lo sile eko.

## Ijoba Gbogun Ti Awon Onifayawo

Ijoba Nigeria nfi oju awon Onifayawo ri nkan.

Larin osu mejila ti o koja, oja faiyawo ti Ijoba gba lowo awon Onifayawo je elegberun-marundinlogoji ponun (£35,00).

Awon Onifayawo ti owo Ijoba te je Egbaje enia (14,000). Siga ati Oti ni o poju ninu eru faiyawo ti Ijoba ri gba lowo awon "Gbekuta" enia wonyi.

Awon miran ninu won tun wo ewon pelu ofo owo ti nwon se.

E ko ha ni da ise ole yin buruku yi duro, ki e wa ise alafia se?

## Asenl Nse Ara Re

A gbo irohin wipe okunrin kan ti a npe ni Alli, ti o si je okan ninu awon ijoye ile Iraq fi etu Bombu kan ranse si okunrin kan ti a npe ni Alli khan nile India. O si ti se eto wipe, nigbati o ba nfa okun ti o gbohin, yio fa oko etu oloro yi.

Nwon ti se etu Bombu na ti o je wipe bi enia ba gbe sanle ko le gbina. A gbo pe okunrin na pe ju ki o to fi ranse. nipa be ko ba oko reiuwe.

Sugbon awon Post Office se asme nipa fifi Bombu na sinu awon eru ti o nlo si ilu Amerika. Nigbati eru na de Amerika ti nwon ko mo eniti o nje Alli Khan, nwon da a pada si ilu Iraq.

Li asiko yi ni Alli ti Iraq to fi eru na ranse ko si nile, Sugbon nwon gbe eru na fun iyawo re Iyawo na bere si tu eru na nibiti o ati u lowo ni bombu na gba ina, o pa iyawo na, o si pa omo re obinrin.

Nwon te waya si Alli wipe, ki o yara ma bowa, nkan ti sele nile. Nigbati o de, ti o bere wipe kili ohun ti o bere wiPe kili ohun ti o pa won bayi nwon si fi bobu na han a.

Nigbati o ri i nse lo fi owo mu ori ti o si kigbe Laila, ilalahu, on li o se ara on bayi? Nigbati awon Olopa gbo gbolohun yi, nwon ba se ejo wipe on lo pa iyawo re ati omo re laimo. nwon fi si ewon osu mefa nitori ejo ko se ro

## Owo-Ori P'ora Nilu Ibadan

A gbo wipe owo bi ponun marunlelogofa (£125) lo di awati nile ise Owo-Ori ti awon Igbimo Olutoju ilu Ibadan.

A ti yan awon Asiro-owo ti Ijoba (Government Auditors) lati se ofintoto gbogbo lwe Owo-ori, Oga awon Asiro-owo si bere si se ise lori awon iwe Owo-ori ti odun 1954 titi de awon iwe ti odun 1955.

Nitori eyi, nwon ti da asiko isinmi Ogbeni Baoku to ni lati gba duro di igbati awon ba pari iwadi na.

A si gbo wipe awon akowe Olowo-ori meta ni awon olopa ti pe wa wi t'enu won nipa owo to s'onu na.

Bi o ba ti jasi, ao ma ta omitoro re si enyin Okawe wa leti.

## Ijoba Ko, Egungun F'ake Ko'ri

**Ibadan** Won ti nse Egungun odun nilu Ibadan,ti odunni yato, a gbo wipe Ijoba kan niso pe nwon ko gbodo lo egba atori, eyiti awon "Gbaruku" bi ede Tapa, ti won je omo-lehin Alapasanpa ma nfi da ijogbon sile.

Alapasanpa si so wipe ko ba on l'aramu lati jade lai si egba atori, nigbati oro Ijoba pelu Alapasanpa ko dogba mo arawon bayi mu ki Oloko Alapansanpa f'ake kori wipe Egungun on ko ni jade.

Eyi mu ki ere odun Egungun ti odunni din kan pataki A tun gbo wipe Egungun pataki kan be ti nwon npe ni Atipako tun gbe Alapansanpa lese, on na ko ko jade.

L'ododo, ohun isedale ilu Ibadan ni Egungun odun ti nwon ma nlo egba atori nigbati aiye wa lowo awon enia wa, itu-kitu ti nwon ba si fi egba atori na pa, a segbe ni.

Sugbon l'aiye olaju ti wa oni yi, o ye ki a ma ko gbogbo iwa jagidijagan wa danu, ki a si tele ilana to dara ti awon amoba, iyen ni awon asiwaju wa ba fi le'le, ki nkan ba le tu ki o si baa fun wa

Iran ti enia ba wo to di ero ile Iwosan, (Hospital) ha dara to, laiye sisiyi ti o je wipe gbogbo omo ti di onise Oba akowe Omo'le (Bricklayer), ti nwon ko je de idi ise agbe, eyiti awon baba wa fi nse ise se tele ri. Eniti o ba nse ise wonyi ti a si so di ero ile Iwosan toripe o lo wo iran Egungun, kini ko ti wi nibi ise awon oyinbo to gbe njeun.

# Iwa Apania

**Salisbury** Okunrin kan to nse ise agbe o gbin Ewe taba, l'o fi bulala na okan ninu awon alawo dudu to nsise lodo re pa bambam.

Nigbati owo awon olopa te ti nwon mu lo siwaju Adajo, awon agbagba aladaro-ejo (Jury) ti Ijoba yan ro oro losiwaju, nwon ro sehin, lehin odidi ojo merin ti nwon fi ro ejo na, nwon so wipe o jebi ipania.

Odaran na ko ri ejo pataki kan ro ju wipe enia dudu na ji on l'aso ko lo. Adajo fi idajo re si igbamiran.


## Chairs For Rent

APPLY

OFE

NO. 3, AIBU STREET LAGOS


## Western Region Medical Services

VACANCY FOR SENIOR STORES EXAMINER

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Senior Stores Examiner in the Western Region Medical Service

Scale of Salary:- D4A; £465-25-615.

QUALIFICATIONS:- Candidates must have had a good general education and practical experience in Store Work. A good knowlege of accounting is also desirable. Candidates must be of high moral integrity and possess good address. They must have had or be able to acquire within reasonable time a good knowledge of costing and Crown Agents indenting procedure and principles of storkeeping as practised in Government Department Stores. Actual experience in a medical Store as well as familiarity with the different kinds of Hospital Supplies enumerated in the Medical Store Catelogue will be an advantage. Candidates in the Government Service should have reached the grade of First Class Clerk or its equivalent,

DUTIES:- The Officer appointed will be required to check ledger records and store cards against actual stock balance in an allocated Medical Stores and, in the near future, unallocated Medical Stores. He will be responsible to the Senior Pharmacist in charge Western Region Medical Stores for compiling a report on each examination.

METHOD OF APPLICATION:- Application should be addressed to the Director of Medical Services Western Region Ibadan so as to reach him not later than the 31st July 1955.

Applications from candidates in Government Service should be submitted through the Head of the applicant's Department and be accompanied by a Confidential Report on the new Confidential Report Form.



## Ile Igbimo Mesan Fun Warri

A gbo wipe Ile igbimo mesan ni Ijoba-Iwo Orun yoonda fun ilu Warri ati Agbegbe re.

Oloye Arthur Prest ti a nwo aworan re yi, yio je okan ninu awon oloye ibile ti yio ni ijoko ninu Ile Igbimo nla ti ilu Warri gegebi aye oye re ti anpe ni Olorogun ti ilu Warri.

## Jamba Se Ole, Onihun Kigbe!

**Eko** Jiosi ole, barawo, ko jeki gbogbo awọn aladugbo ni Idita fi oju kan orun ni oru ọjọ Alamisi mọju ọjọ Jimọ ti o koja lọ yi nigbati ọmọ Jaguda kan lọ ba afọju Onibara ti o sun ni Mọṣalaṣi Idita.

Bi ọmọ Jaguda na ti fi ọbẹ ge owo afọju yi, ni afọju taji, ọwọ ti Afọju na kongẹ agbada ọmọ Jaguda l'ọte, o dimọ agbada Ọlọṣa yi, o wa nkigbe bayi:- Ole, Ole, Barawo.

Ọmọ Jaguda bọ agbada rẹ silẹ fun Afọju nigbati Afọju ko ju silẹ ṣugbọn o gbe pọọn-mẹrin afọju lọ. Onibara ko ri owo rẹ mọ, bẹni ọmọ Jaguda ko ri agbada rẹ mọ.

Eyi ni wipe jamba ṣe Ole, O ṣe Afọju Onibara.

## Agbo Meji Ki Imu Omi Ninu Koto Kanna

**Eko** Ni ọjọ Monday ọsẹ yi ni Ọba Adẹniji Adele II gba Ọmọ-Oye, Ọgbẹni Tawalu Adisa Bello, ti awọn Oloye rẹ mu wa fun ifijoye Onisẹmọ ti ilu Eko.

Awọn enia meta l'o ndu oye na, ṣugbọn ki oniti Ọba gba gẹgẹbi oniti awọn ebi ati awọn Oloye yan to ti Iga Oba kuro ni awọn meji ti nwọn ko fi jẹ, ti lọ gba Iga Onisẹmọ joko si, ni Great Bridge Street, ni Idumota. Awọn eni meji na ni Ogbẹni Lasisi Bakare Fagbayi ati Ọgbẹni Buraimọ Raji Onitọlọ.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ogunlọgọ Olẹpa Ọba ti de ti nwọn si duro ki o ma ba si ija ni Iga Onisẹmọ ni Idumota.

### IKILỌ FUN AWỌN ENIA

Ọba Adele keji ṣe ikilọ fun awọn alatilẹhin Tawalu Adisa wipe ki ẹnikẹni maṣe ja, ki nwọn ma si ṣe fa ijọgbọn, ki olukuluku ṣe jẹjẹ. Ọba Adele so wipe Bello ni eniti o ni ẹtọ, ti awọn enia rẹ yan, ti on ati awọn Oloye on si gba.

Alaiyeluwa Ọba Adele kilọ fun wọn wipe ki nwọn maṣe mu wọ'le l'agbara, nitoripe on ko fẹ ija, o so wipe o da on loju pe nigbati nwọn ba de fila Oye fun Bello, awọn to fi ara wọn joye yio fi Iga silẹ.

Agbo meji ko ni mu omi
ninu koto kanna.
O Ṣeriwọ


## Iwora

Nigbati ara enia ba nfẹ gan Ohun ti o nfa a ni wipe nigbati Kidinrin enia ko ba sisẹ daradara arun iwora yi ni ikilọ fun oluwa rẹ lati mọ wipe Kidinrin ko sisẹ to niyorisi ewu nbọ ti enia ba nlo egbogi yiyara ri alafia.

Ohun pataki ti o fa arun wa fun enia ni wipe idoti pọ ninu ẹjẹ oluwa rẹ, lo dan egbogi De Witt wo fun ra rẹ o le jẹ ohun ti o nfẹ lọ ra ọkan wo ninu sọbu egbogi.



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba sise tara, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio dewi oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti sise. Danwo lo ra ni sobu egbogi.

**DeWITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles


## Iyawo Dun L'osingin!

Ọgbeni Adamoh Y. Agoro osise John Holt nilu Warri ti de si Eko nisisiyi fun ti Igbeyawo omo re, Omidan Tayibatu Ejire Agoro.

Ọgbeni Bashiru osise P.W.D. ni Ijora ni oko iyawo, ni ojo ose (Sunday) ojo kewa osu July, 1955 yi ni nwon o se Igbeyawo na, nile baba iyawo ni 116, Alakoro Marina L'eko

KI OLUWA MU OJO RO O.


## Imoran Fun Eyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹwa ra **Omorela** O dara pupọ fun awọn ọmọde

A ma jo ki ọmọde ri arun sun daradara, o dara fun otutu iko ati orişirişi arun miran ti o ma nba ọmọde ja ni asiko ebin. Ọpọlọpọ abiyamọ lọ ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde.

# Ọmorela Baby Mixture

ŞILE MEJI ABỌ (2/6d) FUN IGO KAN
O wa lodo:-

# Commercial Medicine Stores

QUALIFIED CHEMIST
10, Victoria Street Lagos



# Polowo Ọja Re Sinu Eleti Ọfe



## Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.

J. A. JO BROTHERS
Medicine Store
7, Egerton Road, Lagos



ENJOY YOUR OWN SONGS



SUNG BY YOUR OWN PEOPLE IN THE WAY YOU LOVE MASTERLY RENDERING OF ... AFRICAN MUSIC IS YOURS ON

OBTAINABLE FROM:

**The Association Of Nigeria Gramophone Dealers**

THROUGHOUT NIGERIA



NOW, AVAILABLE

BUGLES, BEDSTEADS PAINTS DISTEMPERS, SAFES Etc.
Just write, Call, or Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28, Balogun Street, (P. O. Box 395) Lagos AND NEW COURT ROAD IBADAN

## Yorubas Beat Ibos 4-2

### TO WIN ALEX ONI'S CUP AGAIN

By BASH. OLUKOTUN

Over 10,000 spectators thronged the Local King George V Stadium last Sunday with some disappointed when the not two strong Yorubas captained by Skipper Situ, outclassed and outplayed the Ibos 4-2 to win the Alex Oni's Cup. It will be recalled that Yorubas have been winning the Cup, but only once did the Ibos got it.

The first half ended 3-1 against the Ibos. Salvador put in the three goals for Yorubas with Ironkwe the only goal for Ibos. On the resumption, Ekunsunmi registered the fourth goal for Yorubas with a cannon shot after dribbling Ekwunob and Anekwe.

Before the close however, Ironkwe took advantages of Jaji Yoruba goalie who ran out of the goal rammed in their second goal.

Father D. J. Slattery controlled the game excellently.

EDITORS NOTE-- We strongly oppose the publication of the Sunday Times „THIS IS THE LAST" All over the World the inter-tribal matches are played, why then will it not continue in Nigeria.

## Oil Expert From U. S. A. Will Advise Shell-D'arcy On Akukwa High Pressure Gas

Just arrived in Nigeria by specially-chartered 'plane are two oil experts from the U. S. A. who have come to advise Shell-D'Arcy on the control of their high pressure gas well at Akukwa, near Awka.

They are internationally-known MYRON M. KINLEY who has had world-wide experience in the control of abnormal gas pressures, and JAMES A. WIRTENSOHN.

As a precautionary measure it may be necessary to pipe he gas some distance away from the well and burn it throuh a flare to render it harmless. It will then be safe for work to continue on the well for the remaining sealin off operations.

## Tani Nfi Qba Sere?

A ko se le so wipe, nitori ti aiye ti di aiye oyinbo ki a ma fi oju egbo tele-Ose aiye baje. Olori nna oja oko. Alaiyeluwa oba Adele keji pase wipe Bello ni oye Onisemo to si, awon enia kan nlo lumo sinu Iga Oloye na. Bi o ba to atisu, idi yio lanu.

## QGBENI MOHAMMED ALI DI ALAKOSO IJOBA PAKISTAN

Qgbeni Mohammed Ali ni eniti won yan ni Alakoso Ijoba Ilu Pakistan (Prime Minister) dipo Qgbeni khwaja Nazimuddin to ti je Alakoso Ijoba Pakistan ri, ti nwon ti yo. Gomina Agba ilu Pakistan Qlola Chulam Mohammed lo yan an.

Nipa ikede Alakoso Ijoba Pakistan to so wipe Ilu Pakistan ti pa ero po pinnu wipe awon yio faramo adehun ipapo mo ilu Iraq, eyiti o je didun ninu ilu Oyinbo Gesi, (U.K.) bi o ti je wipe lati osu April



ni Gesi ti f'aramo.

Inu Ijoba Gesi dun to be ti alakoso Ijoba Gesi Sir Anthony Eden fi ranse pada si Qgbeni Mohammed Ali wipe ikede ti Ijoba Pakistan se yi dun mo Ijoba Gesi ninu nitoripe ajumosepo awon yio ma lo deedee.

### IGBESI AIYE MOHAMMED ALI

O ye ki a so die ninu itan igbesi aiye Qgbeni Mohammed Ali fun enyin okawe wa. Abi Mohammed Ali si aiye nilu Bogra ninu odun 1909, ni apa Ila-Orun Bengal Ile Eko giga ti Calcutta ni o koko gba oye B.A. ni odun 1930. O bere ise iselu nwon si yan si ipo Alaga Igbimo aselu (Mayor) ni asiko na lo da ile eko kan sile ti on na je alakoso fun ile eko na.

Ni odun 1937 ni nwon yan si Igbimo Asofin apapo ilu Bengal, ati ni odun 1943 li o di akowe alakoso (Prime-Minister) ilu Bengal, ni odun 1946 l'a tun yan si ipo olutoju-owo ati alafia ilu, o si se ile de alakoso ilu Bengal nigba pupo.

Qpolopo ohun anfani l'oda sile, awon nkan bi Lake Hospital nilu Culcutta, Ile ikose ogun ni Dacca, (Medical College) ati Ile-itoju iko jedo-jedo ni ilu Nadia.

Nigbati Mohammed Ali wo'le Igbimo nla ti Paksistan a yan si ipo asoju ilu Pakistan si ilu Burma ni odun 1948. A yan si ipo nla alabojuto nilu Canada ninu odun 1952 l'ayan fun ipo asoju ilu Pakistan ni Amerika. On l'o tun di Alakoso ilu Pakistan l'odun ni. (Premier).

## Oti Ijogbon L'oti Sogomu

EKO- Qgbeni kan ti oruko re nje Oleyede Oyedele to ngbe abule Ojo-Oniyun l'Ebute-metta l'a gbo wipe awon olopa oba ramu fun esun oti mamu-oko-jina ti nwon npe ni Oyinbogo li o so niwaju adajo ni Kotu Yaba wipe otito ni on ni oti na lowo, sugbon on ma nfi gbona ara ni.

Adajo ni aso otutu (Bulan keti) mbe l'ogba ewon ti o ma fi gbona ara; nitorina ki o san ponun mewa tabi ki o lo gbona ara re l'osu meji l'ogba ewon.

Eyi nko o! enyin ara wa.

## KILO PA BQLAJI KASALI

Eko Ejo iku to pa Bolaji Kasali ti nwon ri oku re ninu Ira nilu Ikorodu ti nwon fi siwaju adajo Ikeja ni a gbo wipe nwon fi ejo na ranse si Ijebu-Ode, wipe kotu Ijebu-Ode l'o ni eto lati gbo ejo na.

Enyin Okawe wa yio ranti wipe Bolaji Kasali yi ni eniti a gbo wipe o re re kan pe jade ni ale ojo Satide ti ojo Kerinla osu May, ti ko si pada si ile re mo. Lehin ojo marun ni nwon to ri oku re ninu Ogodo.

Awon enia mokanla ni awon Qlopa ma fi sun esun ipania fun iku Bolaji Kasali. Awon enia na ni Tukuru Shonubi, Jimo Qluwole, Idowu Bada, Abudu Aluko, Raflu Odutola, Jegede Emanuel, Sunmola Yisa, Oluwole Iluku, Odu Ogun, Fitini Onibudo ati Braimo alatilehin. Odi ojo ketala osu July, ki nwon to bere ejo na ni Ijebu-Ode.

REDIFFUSION
THE BOX THAT TALKS SINGS & BRINGS MUSIC TO YOUR HOME
Costs less than 3d a day and gives you pleasure for 17 hours.
MAINTAINANCE FREE! ARE YOU A SUBSCRIBER?

Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370